

# Jẹ́ Ká Kàwé

Ìwé Akẹ́kọ̀ọ́

Kíláàsì 3

Sáà 1 — 3

Yorùbá

USAID FROM THE AMERICAN PEOPLE

THE INITIATIVE

# Jẹ́ Ká Kàwé

## Ìwé Akẹ́kọ̀ọ́

Kíláàsì 3

Sáà 1 — 3

Yorùbá

This early grade reading material for primary teachers and pupils in Nigeria is made possible by the support of the American people through the United States Agency for International Development (USAID) under the The Initiative program (Contract Number AID-620-C-15-00002).

First edition, 2021

Rights and permissions

The text and illustrations in this work are licensed under the Creative Commons Attribution 4.0 International License. To view a copy of this license, visit http://creativecommons.org/licenses/by/4.0/.  Under the Creative Commons Attribution license, you are free to copy, distribute, transmit and adapt the work as long as you attribute or credit the original author or illustrator. In the case of this book use the following attribution language: “Developed under the USAID funded The Initiative program and licensed under the Creative Commons Attribution 4.0 International License.”

---

Ìwé kíkà fún àwọn èwe tí a ṣe àgbéjáde rẹ̀ fún àwọn olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní Nàìjíríà wáyé pẹ̀lú àtilẹ́yìn àwọn ara Amẹ́ríkà nípasẹ̀ àjọ United States Agency for International Development (USAID) lábẹ́ ètò The Initiative (Nọ́ḿbà Ìwé-Àdéhùn: AID-620-C-15 -00002).

Àtẹ̀jáde kìn-ín-ni, 2021

Ẹ̀tọ́ àti Ìgbànìláyè

Àwọn ọ̀rọ̀ àti àwòrán tí a lò nínú iṣẹ́ yìí wà lábẹ́ ìwé-àṣẹ kárí-ayé ti àjọ Creative Commons Attribution 4.0. Láti ṣe àyẹ̀wò ìwé-àṣẹ yìí, ṣe àbẹ̀wò sí http://creativecommons.org/licenses/by/4.0/. Lábẹ́ àṣẹ àjọ Creative Commons Attribution, ẹ ní òmìnira láti ṣe ẹ̀dà, pín káàkiri, ṣe àgbéjáde, àmúlò tàbí àyálò lára iṣẹ́ yìí níwọ̀n ìgbà tí ẹ bá ti lè gbé oríyìn fún òǹkọ̀wé tàbí ayàwòrán ìpìlẹ̀ iṣẹ́ yìí. Láti gbé oríyìn fún ìpìlẹ̀ iṣẹ́ ìwé yìí, ẹ lo àṣàyàn gbólóhùn yìí: “A ṣe àgbéjáde iṣẹ́ yìí lábẹ́ àṣẹ àjọ USAID tó jẹ́ agbátẹrù ìnáwó fún ètò-ẹ̀kọ́ The Initiative àti lábẹ́ Ìwé-Àṣẹ Kárí-Ayé ti àjọ Creative Commons Attribution 4.0”

# Àtẹ Àkóónú

**Ìdúpẹ́ ........................................ vi**

**Àwọn Òǹkọ̀we ........................................ vii**

**Ọ̀rọ̀ À kọ́sọ lá ti ọ̀dọ̀ À jọ NERDC ........................................ ix**

**Ìfáárà ........................................ xi**

**Sáà 1 ........................................ 1**

Ọ̀sẹ̀ 1 ........................................ 2
Ọ̀sẹ̀ 2 ........................................ 8
Ọ̀sẹ̀ 3 ........................................ 14
Ọ̀sẹ̀ 4 ........................................ 20
Ọ̀sẹ̀ 5 ........................................ 26
Ọ̀sẹ̀ 6 ........................................ 27
Ọ̀sẹ̀ 7 ........................................ 33
Ọ̀sẹ̀ 8 ........................................ 39
Ọ̀sẹ̀ 9 ........................................ 45
Ọ̀sẹ̀ 10 ........................................ 51

**Sáà 2 ........................................ 52**

Ọ̀sẹ̀ 1 ........................................ 53
Ọ̀sẹ̀ 2 ........................................ 58
Ọ̀sẹ̀ 3 ........................................ 65
Ọ̀sẹ̀ 4 ........................................ 71
Ọ̀sẹ̀ 5 ........................................ 77
Ọ̀sẹ̀ 6 ........................................ 78
Ọ̀sẹ̀ 7 ........................................ 84
Ọ̀sẹ̀ 8 ........................................ 90
Ọ̀sẹ̀ 9 ........................................ 96
Ọ̀sẹ̀ 10 ........................................ 102

**Sáà 3 ........................................ 103**

Ọ̀sẹ̀ 1 ........................................ 104
Ọ̀sẹ̀ 2 ........................................ 110
Ọ̀sẹ̀ 3 ........................................ 116
Ọ̀sẹ̀ 4 ........................................ 122
Ọ̀sẹ̀ 5 ........................................ 128
Ọ̀sẹ̀ 6 ........................................ 129
Ọ̀sẹ̀ 7 ........................................ 135
Ọ̀sẹ̀ 8 ........................................ 141
Ọ̀sẹ̀ 9 ........................................ 147
Ọ̀sẹ̀ 10 ........................................ 153

# Ìdúpẹ́

Àkójọpọ̀ àwọn olùkọ́ni àti àwọn amòye ló ṣe àgbékalẹ̀ ètò ìwé-kíkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí lábẹ́ ìtọ́sọ́nà àjọ Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC) àti àjọ USAID tí ó ṣe agbátẹrù ìnáwó iṣẹ́ yìí fún àjọ The Initiative. A le rí orúkọ àwọn olùkópa iṣẹ́ yìí ní oju-iwe iii. Ọ̀jọ̀gbọ́n Ismail Junaidu, Ọ̀gá-Àgbà àjọ NERDC, ṣe àtìlẹ́yìn fún ètò yìí láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ títí dé ìparí. Denise O'Toole àti Dr. Nura Ibrahim láti àjọ United States Agency for International Development (USAID) ṣe àtìlẹyìn pẹ̀lú ìtọ́sọ́nà àti ìmọ̀ràn ní gbogbo ipele àgbékalẹ̀ ètò iṣẹ́ yìí. Ọ̀mọ̀wé Nuru-deen Lawal, Lydia Ezihe Onuoha, Mark Hamilton, Zahra'u Abubakar Maishanu, Zaliha Nasiruddeen Bello, Joy du Plessis, Mary Sugrue, àti Corrie Blankenbeckler lo ìmọ̀ ètò ìwé-kíkà wọn láti ṣiṣẹ́ takuntakun fún àgbéjáde iṣẹ́ yìí. Àjọ SIL International ṣe àtilẹ́yìn fún àgbékalẹ̀ kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù tí a nílò láti ṣe ìtọ́ni fún kíkọ àwọn ìwé kikà titun náà nípa ṣíṣe àmúlò ọgbọ́n àtinúdá ti ìmọ-ẹ̀rọ Synphony. Ọ̀mọ̀wé Nasir M. Baba ni ó ṣàbójútó iṣẹ́ náà nígbà tí Ọpẹ́yẹmí Ogúnlẹ́yẹ ṣe ìpèsè ìlò ẹ̀rọ ìkànsí-ara-ẹni fún ìpàdé ìfọ̀rọ̀wérọ̀ orí ẹ̀rọ. Àwọn tí ó ṣe ìyàwòrán gíráfîìkì inú iwé náà ni Godwin Ondoma, Samson Lawrence, Christian Ikpe, àti Aliyu Sani. John Àkànbí Nhorj, Aliyu Sani, Ernest Ibe àti Uche Idu ni àwọn aṣàpèjúwe àwòrán inú àwọn ìwé náà.

# Àwọn Òǹkọ̀wé

| Orúkọ | Adírẹ́sì tàbí Orúkọ Ilé-Iṣẹ́ |
|---|---|
| Adeleye Timilehin | National Commission for Colleges of Education, Abuja |
| Adeosun Adetayo Joseph | Olabisi Onabanjo University, Ago Iwoye |
| Adepoju Folasade Funmilayo | Jagunmolu Girls' Senior Secondary School, Bariga, Lagos |
| Adeyemi Abiodun Adeyinka | University of Ibadan |
| Adigun Fatima Dasola | National Commission for Colleges of Education, Abuja |
| Aisha Bamanga | Universal Basic Education Commission, Abuja |
| Akinwande Olaide | Foursquare International School, Asero, Abeokuta |
| Alawiye Basheer Adisa | Lagos State University, Ojo |
| Audu Rosemary Busayo | Lagos State University, Ojo |
| Bakare Olatunji Babatunde | Michael Otedola College of Primary Education, Noforija-Epe |
| Bilyaminu Bello Inuwa | Bayero University, Kano |
| Bukola R. Adeleke | Ìṣẹ̀dálẹ̀ Media concept |
| Dámiláre Samson Oyèdélé | Yorùbá di Wúrà, Lagos |
| Daniel Abiodun Oluwafemi | No. 7, Abokanle, Street, Sekona, Ede |
| Dr. (Mrs.) Iyabode Deborah Akande | Obafemi Awolowo University, Ile-Ife |
| Dr. Margaret Lawani | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |
| Dr. Mark Hamilton | The Initiative |
| Dr. Michael Olugbenga Ajileye | Alvan Ikoku Federal College of Education, Owerri |
| Dr. Oyedeji Victor Abimbola | Federal College of Education, Zaria |
| Dr. (Mrs.) Elizabeth Adebisi Banjo | University of Lagos, Akoka |
| Iyabode Baliquis Alaga | University of Ibadan |
| Lydia Ezihe Onuoha | The Initiative |
| Mary Ogbene Abah | Teachers' Registration Council of Nigeria, Abuja |
| Moses Ayọ̀bámi Oyèdélé | Yorùbá di Wúrà, Lagos |
| Mr. Aina Opeyemi | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |
| Mrs. Babalola Victoria Olubanwo | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |

| | |
|---|---|
| Mrs. Afolayan A. Funmilayo | Kwara State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Ipinlaye Omolola | Ondo State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Jumoke Fagbohun | Ekiti State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Kolade Bose O | Osun State Univeral Basic Education Board |
| Mrs. Ladipo Olaide | Oyo State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Olayinka Ogungbayi | Ogun State Universal Basic Education Board |
| Nurudeen Lawal | The Initiative |
| Ojo Olubunmi Ayobami | The Bridge College, Abeokuta |
| Olayinka Phebe Olayemi | Federal Government College, Ijaniki |
| Omotoyosi Ishola | Camilla Brook Place School, Lagos |
| Opeoluwa Taiwo | University of Ibadan |
| Patience Abiodun | Lagos State Universal Basic Education Board |
| Prof. Oluyemisi Adebowale | Adekunle Ajasin University, Akungba-Akoko |
| Professor Solomon Olanrewaju Makinde | Lagos State University, Ojó |
| Rifqat Opeyemi Sanni | Adeniran Ogunsanya College of Education, Oto/Ijanikin |
| Sakiru Kazeem Adeniyi | Adeniran Ogunsanya College of Education, Oto/Ijanikin |
| Segun Adenipekun Olanibi | Aminu Saleh College of Education, Azare |
| Sulaymon Muhammad Raji | Adeyemi College of Education, Ondo |
| Zaliha Nasiruddeen Bello | The Initiative |
| Zahra'u Abubakar Maishanu | The Initiative |
| Olatunde Bamidele Eniola | Lagos State Universal Education Board |

# Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ

Ìmọ̀ ìwé-kíka ṣe pàtàkì fún àwọn ọmọde láti lè ṣe àṣeyege ní ilé-ẹ̀kọ́ àtí ní ìyókù ìgbé-ayé wọn lẹ́yìn tí wọ́n bá parí ẹ̀kọ́ wọn. Síwájú sí i, ìlànà ìkọ́ni ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé àti ìtọ́sọ̀nà tó péye ṣe pàtàkì jọjọ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè ní ìmọ̀ tí ó yè kooro nínú ìwé-kíkà, ní pàtàkì jùlọ láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ẹ̀kọ́ wọn. Àbájáde iṣẹ́ ìwádìí ni orílẹ̀ èdè-Nàìjíríà àti ní àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn ti fi hàn kedere pé ìlànà ìkọ́ni àti ìtọ́sọ̀nà tó yè kòoro ló lè mú ìdàgbàsókè bá ìmọ̀ọ̀ṣe nínú ìwé-kíka àwọn ọmọdé láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ayé wọn. Ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìfàsẹ́yìn púpọ̀ nínú ìmọ̀ ìwé-kíkà. Èyí ló mú kí àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀ nínú ètò-ẹkọ jákè-jádò àgbáyé fẹnu kò láti gùn lé àṣeyọrí ètò ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà tí àwọn ìpínlẹ̀ mélòó kan ni orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tí ń múlò. Àwọn ìgbésẹ̀ yìí ṣe pàtàkì láti lè mú ìlọsíwájú tó péye bá ètò ìkọ́ni àti ìkẹ́kọ̀ọ́ ní jáke-jádò orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Fún ìdí èyi, inú mi dùn láti ṣe àfihàn ètò tuntun tí a pè ní *Jẹ́ Ká Kàwé!* tí ó wà fún ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ (kíláàsì kìn-ín-ní títí dé ìkẹ́ta) ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

Pẹ̀lú àjọṣepọ̀ gidi láàrin ìjọba àpapọ̀ àti àwọn ìjọba ìpínlẹ̀, pẹ̀lú ìnáwó tó péye láti ọ̀dọ̀ àjọ USAID, àjọ The Initiative Project ṣe àtìlẹyìn ńlá fún àgbéjáde àwọn ìwé kọ̀seémánìí yìí láti mú kí ìkọ́ni àti ìkẹ́kọ̀ọ́ ìwé-kíkà ní àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá ní ìhà gúúsù orílẹ̀-èdè Nàìjíríà le kún ojú òṣùwọ̀n. A dúpẹ́ gidigidi lọ́wọ́ àjọ *United States Agency for International Development (USAID)* fún ìrànlọ́wọ́ wọn èyí tí o mú kí àgbéjáde àkànṣe iṣẹ́ yìí wáyé, èyí tí ó sì fún wa ní ìdánílójú pé àṣeyọrí tó tẹ̀wọ̀n nínú ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọdé jẹ́ ohun tó ṣeéṣe.

Ètò tuntun tí a mọ̀ sí *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí wáyé ní àsìkò tí ó tọ́ tí ó sì yẹ, gbogbo ara ni a sì fi ṣe àtìlẹ́yìn fún ètò yìí. Láìṣe-àní-àní, ètò kárí-ayé ni ètò ìdàgbàsókè ìmọ̀ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọdé, orílẹ̀-èdè wa Nàìjíríà kò sì kẹ̀rẹ̀ rárá nínú àtìlẹ́yìn wa fún ètò náà. Àgbékalẹ̀ ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí tẹ̀lé àwọn ìlànà ìkẹ́kọ̀ọ́ káríayé tí ó dára jùlọ fún ìwé-kíkà, pẹ̀lú ìtọ́nisọ́nà, ọgbọ́n àti ìrírí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀ onímọ̀ ìkọ́ni, onímọ̀ èdè Yorùbá, àti àwọn onímọ̀ kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù káàkiri àwọn ìpínlẹ̀ àti láti ọ̀dọ̀ ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Àgbékalẹ̀ àwọn ìwé yìí sì tún tẹ̀lé àwọn ìlànà ẹlẹ́rìí tó dájú fún ìtọ́nísọ́nà lórí ìwé-kika tí a ti lò pẹ̀lú àbájáde tó gbé ògo yọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ní àwọn orílẹ̀-èdè mîírán káàkiri àgbáyé.

Àṣeyọrí ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí wà lọ́wọ́ àwọn olùkọ́. Àwọn ni agbátẹrù àkọ́kọ́ fún àṣeyọrí ètò yìí. Ìmọ̀, ìfẹ́-inú àtí agbára wọn ṣe pàtàkì fún àbájáde ètò yìí. Nítorí náà, o ṣe pàtàkì pé kí gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ ẹ̀kọ́ jẹ lógún fọwọsowọ́pọ̀ láti rí i dájú pé àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ rí àtìlẹ́yìn tó péye gbà láti lè ṣe ìrànwọ́ fún àwọn ọmọ wa lórí ìmọ̀ ìwé-kíkà. Kí èyí le ṣeéṣe, àwọn olùkọ́ níláti máa ṣe ìtọ́nisọ́na àti àtìlẹ́yìn fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti mú ìwé-kíkà àti ìwé-kíkọ lóòrè-kóòrè bí iṣẹ́.

Àwọn òbí náà ní ipa pàtàkì láti kó nípa ṣíṣe kóríyá fún àwọn ọmọ wọn láti máa ṣe iṣẹ́ ìwé-kíkà àti ìwé-kíkọ láyè ara wọn nígbà gbogbo àti láti rí i pé àwọn ọmọ ń lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ lásìkò àti lójoojúmọ. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, àwọn òbi gbọ́dọ̀ rí i dájú pé àwọn ọmọ wọn ní ìfẹ́ sí ìwé-kíkà. Yàtọ̀ sí àwọn ọ̀nà ìkọ́ni tí olùkọ́ ń lò, ìfẹ́ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá ní sí ìwé-kíkà ni yóò ṣe atọ́kùn ìfẹ́ tí wọ́n máa ní sí ètò ẹ̀kọ́ ní gbogbo ọjọ́ ayé wọn, èyí tí ó sì máa ṣe okùnfà àṣeyege ní ilé-ẹ̀kọ́ àtí lẹ́yìn tí wọ́n bá parí ẹ̀kọ́ wọn.

Àwọn alákòóso ètò ẹ̀kọ́ ní gbogbo àwọn ìpínlẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá gbọ́dọ̀ rí i pe wọ́n ra ohun-èlò pàtàkì fún ìwé-kíkà yìí, kí wọ́n si rí i pé àwọn ìwé yìí dé ọwọ́ gbogbo àwọn olùkọ́, àwọn

akẹ́kọ̀ọ́ àti gbogbo ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ jáke-jádo ilẹ̀ Yoruba. Lára ojúṣe wọn sì tún ni láti rí i pé wọ́n n pèsè ètò ìdàgbàsókè-lẹ́nu-iṣẹ fún àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ lóòrè-kóòrè. Èyí ṣe pàtàkì púpọ̀ fún àṣeyọrí ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí. Ojúṣe gbogbo wa ni lóríl̀ẹ̀-èdè Nàìjíríà yìí láti rí i pé ìpìlẹ̀ ètò yìí fẹsẹ̀ múlẹ̀ dáadáa fún ìlọ́síwàjú ẹ̀kọ́ àwọn ọmọ wa lóní àti lọ́jọ́ ìwájú. A tún rọ àwọn olùkọ́ lẹ́ẹ̀kan sí láti rí i pé wọ́n ń ṣe àmúlo àwọn ìwé yìí lójoojúmọ́ pẹ̀lú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn. Èyí ṣe kókó fún ìdàgbàsókè ìmọ̀ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọ wa. Tí a bá le gbé àwọn ìgbésẹ̀ pàtàkì yìí, ìdánilójú gidi wà pé ọjọ́ ọ̀lá àwọn ọmọ wa, ọjọ́ ọ̀la àwọn abúlé àti ìlú wa, ọjọ́ ọ̀la àwọn ìpínlẹ̀ wa àti ọjọ́ ọ̀la orílẹ̀-èdè wa yóò dára sí i.

**Prof. Ismail Junaidu**

Ọ̀gá Àgbà
Àjọ *Nigerian Educational Research and Development Council*

# Ìfáárà

A ṣe àgbékalè ìwé yìí láti pesè ọgbọ́n àti ìmọ̀ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ọlọ́dún mẹ́ta àkọ́kọ́ nílò fún kíka ìwé ní àkàyé. Ẹ̀rí tí a gbà láti ínú iyàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́ ní ìhà àríwá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí ó lè kàwé ní èdè abínibíbi kò tó nǹkan. Kódà, ìwádìí káàkiri àgbáyé fi ìdi ohun tí ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀-ìkọ́ni ti mọ̀ múlẹ̀ pé: Nígbà tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ bá lè kàwé jágaara pẹ̀lú àkàyé nínú èdè abínibí wọn, ló tó ṣe é ṣe kí irúfẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bẹ́ẹ̀ ṣe àṣeyọrí tó péye nílé-ẹ̀kọ́. Àwọn ìmọ̀ àti ọgbọ́n ìkàwé tí àwọn ọmọdé ti kọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ẹ̀kọ́ wọn yóò ran kíkọ́ ẹ̀kọ́ èdè mìíràn lọ́wọ́ bí ọmọ́ bá ṣe ń dàgbà sí i. Síwájú síi, ìmọ̀ àti ọgbọ́n ìkàwé fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ máa ń ran kíkọ́ ẹ̀kọ́ mìíràn lọ́wọ́ nínú èyí tí ìwé-kíkà pọn dandan. Láìdéènà pẹnu, bí ọmọ ṣe lè kàwé sí wà lọ́wọ́ irú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ọmọ́ náà gbà nínú yàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́.

Àṣeyọrí èto ìwé-kíkà yìí wà lọ́wọ́ ìmọ̀, òye àti ọgbọ́n àwọn olùkọ́ tó ń kọ́ àwọn ọmọ nínú iyàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́, àti ìfarajìn wọn láti jẹ́ kí àyọrisí rere bá ìwé-kíkà. Síbẹ̀, ìfarajìn tí ó lọ́ọ̀rìn nípasẹ̀ ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn òbí àti àwùjọ. Ojúṣe àwọn òbí ni láti rí i dájú pé ẹ̀kọ́ kíkọ́ wáyé, pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti àtìlẹ̀yìn àwọn mìíràn tó wà ní àwùjọ ilé-ẹ̀kọ́. Ọmọ kọ̀ọ̀kan ni a gbọ́dọ̀ fún ní ìwé láti lè mú kí ìwé-kíkà wọn gbilẹ̀ sí i. Àwọn ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ àti àwọn olùkọ́ gbọ́dọ̀ rí i dájú pé ìwé yìí wà ní àrọ́wọ́tó àwọn akẹ́kọ̀ọ́, kì í ṣe èyí tí à ń tọ́jú pamọ́ síbìkan láìlò. Ọ̀fẹ́ ni a gbọ́dọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kí àwọn akékọ̀ọ́ lè ní ànfààní níní àti lílo àwọn ohun-èlo láti lè yege. A gbọ́dọ̀ rí i dájú pé a gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níyànjú láti máa mú ìwe wọn lọ sí ilé. Ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, ó ṣe pàtàkì pé kí àwọn òbí náà máa ran àwọn ọmọ lọ́wọ́ lórí àwọn iṣẹ́-àṣetiléwá, kí wọ́n rí i dájú pé ó yé wọn kí wọ́n sì ṣe é bó ti tọ́ àti bó ti yẹ. Àwọn òbí gbọ́dọ̀ máa kàwé tàbí kà ìtàn sí etí igbọ́ àwọn ọmọ wọn; kí wọ́n máa tẹ́tísílẹ̀ gbọ́ ohun tí àwọn ọmọ wọn ń ká fún wọn, kí wọ́n máa sọ ìtàn fún wọn, kí wọ́n sì máa ran àwọn ọmọ wọn lọ́wọ́ nínú àkọsílẹ̀ nípa ṣíṣe iṣẹ́ yìí lójoojúmọ́. Ìgbà yìí nìkan ni àwọn ọmọ lè yege bí wọ́n ṣe ń dàgbà sí i nínú ìmọ̀ àti ọgbọ́n àti láti ní ìfẹ sí ìwé kíkà - láti kàwé àti láti kàwé náà dáadáa.

A kọ ìwé tí à ń sọ nípa rẹ̀ yìí ní ìbámu pẹ̀lú èròńgbà pé gbogbo ará, ọ̀rẹ́ àtí mọ̀lẹ́bí ọmọ ló ní ipa pàtàkì láti kó nínú ríran ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà ọmọ lọ́wọ́, pàápàá jùlọ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Àwọn olùkọ́ àti òbí ló kó ipa tó ga jùlọ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe là á kalẹ̀ níbí. Síbẹ̀, àwọn olùkọ́ àti òbí gbọ́dọ̀ mọ̀-ọ́-mọ̀ máa ṣe ohun tó máa mú kí ìkẹ́kọ̀ọ́ àwọn ọmọ gbèrú sí i. Ìwé yìí wà fún ìpìlẹ̀ tí a óò mọ lé; ó sì jẹ́ ohun-èlò tó ṣe kókó tí gbogbo ọmọdé nílò láti di olùfẹ́ ìwé-kíkà àti olùfẹ̀ ìkẹ́kọ̀ọ́ ní gbogbo ọjọ́-ayé wọn.



# Sáà 1

# Ọ̀sẹ̀ 1 - 10



# Ilé-iṣẹ́ Bàbá-àgbà

Ọmọ-ọmọ ni Tárá jẹ́ sí bàbá-àgbà.
Bàbá-àgbà ni bàbá ìyá Tárá.
Ìyá-àgbà lọ sí ìlú-ọba.
Ṣùgbọ́n bàbá-àgbà wà ní ìlú Èkó.
Bàbá-àgbà ní ilé-iṣẹ́ ńla ní Èkó.
Àwọn ọmọ-iṣẹ bàbá-àgbà pọ̀ púpọ.
Ẹ̀rọ ńla-ńlá wà ní ilé-iṣẹ́ bàbá-àgbà.
Ilé-iṣẹ́ bàbá-àgbà máa ń ṣe bàtà.

▲ bàbá-àgbà ilé-iṣẹ́ ọmọ-ọmọ
ilé-ẹ̀kọ́ ọmọ-iṣẹ́

## Ẹ̀kọ́ 1



bàbá-àgbà ilé-iṣẹ́ ọmọ-ọmọ

ilé-ẹ̀kọ́ ọmọ-iṣẹ́



bàbá-àgbà ilé-iṣẹ́ ọmọ-ọmọ

ilé-ẹ̀kọ́ ọmọ-iṣẹ́

## Ẹ̀kọ́ 2



bàbá àgbà ilé iṣẹ́ ọmọ ọmọ,

ilé ẹ̀kọ́ ọmọ iṣẹ́



bàbá àgbà ilé iṣẹ́ ọmọ ọmọ

ilé ẹ̀kọ́ ọmọ iṣẹ́



# Ilé Ẹbí Tàlà

Ẹbí bàbá àti ìyá Tàlà tóbi.
Bàbá kọ́ ilé-ẹbi ńlá fún ẹbí rẹ̀.
Ilé bàbá Tàlà ní yàrá-ìkàwé kan.
Yàrá-ìdáná méjì wà nínú ilé náà.
Àwọn mọ̀lẹ́bí ń gbé pẹ̀lú wọn.
Bàbá Tàlà fẹ́ràn àwọn mọ̀lẹ́bí rẹ̀.
Tàlà àti Tárá fẹ́ràn mọ̀lẹ́bí wọn.
Gbogbo wọn máa ń wọ aṣọ-ẹbi.

▲ ilé-ẹ̀kọ́ yàrá-ìkàwé yàrá-ìdáná
aṣọ-ẹbí ìka-ọwọ́

## Ẹ̀kọ́ 3



ilé-ẹ̀kọ́ yàrá-ìkàwé yàrá-ìdáná

aṣọ-ẹbí ìka-ọwọ



ilé-ẹ̀kọ́, yàrá-ìkàwé, yàrá-ìdáná,

aṣọ-ẹbí, ìka-ọwọ

## Ẹ̀kọ́ 4



ilé ẹ̀kọ́ yàrá ìkàwé yàrá ìdáná

aṣọ ẹbí ìka ọwọ



ilé ẹ̀kọ́ yàrá ìkàwé yàrá ìdáná

aṣọ ẹbí ìka ọwọ



# Okùn Ọmọ Ìyá

Ọmọ ìyá ni Tárá àti Tàlà. Ẹ̀gbọ́n wọn ni Gbádé. Wọ́n ń gbé agboolé kan náà. Gbádé bí ọmọkùnrin kan. Gbogbo ẹbí kí wọn kú oríire. Wọ́n ṣe ìkómọjáde lọ́jọ́ kẹjọ. Bàbá-àgbà sọ ọmọ náà ní Àkànbí. Inú gbogbo ẹbí tó péjọ síbẹ̀ dùn.

★ Ọmọ ìyá ni Tárá àti Tàlà. Ẹ̀gbọ́n wọn ni Gbádé.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







## Ìbẹ̀wò Gbádé

Gbádé lọ sí Àwà nígbà ọdún. Ilé baálé ló kọ́kọ́ yà sí. Gbádé fún baálé lówó ọdún. Àwọn ìyàwó ilé kúnlẹ̀ kí i. Gbogbo aráalé ni ó gba nǹkan ọdún. Aṣọ ló fún wọn ní agbo-ilé ìyá rẹ̀. Gbogbo ẹbí gbàdúrà fún un.

★ Gbádé lọ sí Àwà nígbà ọdún. Ilé baálé ló kọ́kọ́ yà sí.

## Ẹ̀kọ́ 3

# Ẹ̀kọ́ 4







# Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Àwọn Eèrà

Oúnjẹ wọ́n púpọ̀ ní oṣù kẹta ọdún. Ọba àwọn eèrà pe ìpàdé gbogbo wọn. Ó sọ fún wọn kí wọ́n wá oúnjẹ lọ. Àwọn eèrà fọwọ́sowọ́pọ̀ láti wá oúnjẹ. Wọ́n tọ́jú oúnjẹ tí wọ́n rí dáradára. Ìyàn mú ṣùgbọ́n ebi kó pa àwọn eèrà. Àwọn ènìyàn béèrè bí àwọn eèrà ṣe róúnjẹ. Wọ́n kọ́gbọ́n ńla lára àwọn eèrà.

★ Oúnjẹ wọ́n púpọ̀ ní oṣù kẹta ọdún. Ọba àwọn eèrà pe ìpàdé gbogbo wọn.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2



# Oúnjẹ Aládùn

Tàlà fẹ́ràn láti máa se oúnjẹ. O máa ń se oúnjẹ aládùn. Tàfá fẹ́ràn iyán pẹ̀lú ọbẹ̀ ẹ̀gúsí. Ó bẹ Tàlà láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún òun. Àwọn méjèèjì jọ gún iyán. Tàlà sì se ọbẹ̀ ẹ̀gúsí tó ta sánsán. Wọ́n jẹ oúnjẹ aládùn. Tàfá dúpẹ́ lọ́wọ́ Tàlà fún ìrànlọ́wọ́ tó ṣe fún un.

★ Tàlà fẹ́ràn láti máa se oúnjẹ. O máa ń se oúnjẹ aládùn.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4



# Àrokodóko

Òjò ńlá rọ̀ ní ìlù Owódé. Òjò yìí fa ìkún-omi tó ba ohun ọ̀gbìn jẹ́. Àwọn àgbẹ̀ pàdánù gbogbo oko wọn. Àwọn alátẹ náà kò lè tajà. Gbogbo àwọn àgbẹ̀ ṣe ìpàdé. Wọ́n fẹnu kò láti ṣe àrokodóko. Iṣẹ́ àgbẹ̀ gbèrú sí i nínú ìlú. Oúnjẹ sì pọ̀ rẹpẹtẹ.

★ Òjò ńlá rọ̀ ní ìlú Owode. Òjò yìí fa ìkún-omi tó ba ohun ọ̀gbìn jẹ́.

## Ẹ̀kọ́ 1





# Ẹ̀kọ́ 2







## Ẹgbẹ́ Alájẹṣẹ́kù

Oníṣòwò ni ìyá Tàfá ní ọjà Owódé. Ọ̀rẹ́ ni ìyá Tàfá àti ìyá Tárá. Ìyá Tárá ṣe àbẹ̀wò sí isọ̀ ìyá Tàfá. Ó bẹ̀ ẹ́ kí ó yá òun lówó díẹ̀ fún òwò. Ìyá Tàfá gba owo nínú ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù. Inú ìyá Tárá dùn púpọ̀. Ó pinnu láti wọ ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù.

★ Oníṣòwò ni ìyá Tàfá ní ọjà Owódé.
Ọ̀rẹ́ ni ìyá Tàfá àti ìyá Tárá.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ____________________

| Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà |
| --- |
| |

**Ìpín 1: Àyọkà**

**Okùn Ọmọ Ìyá**

Ọmọ ìyá ni Tárá àti Tàlà. Ẹ̀gbọ́n wọn ni Gbádé. Wọ́n ń gbé agboolé kan náà. Gbádé bí ọmọkùnrin kan. Gbogbo ẹbí kí wọn kú oríire. Wọ́n ṣe ìkómọjáde lọ́jọ́ kẹjọ. Bàbá-àgbà sọ ọmọ náà ní Àkànbí. Inú gbogbo ẹbí tó péjọ síbẹ̀ dùn.

**Ìpín 2: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Ta ló bí ọmọkùnrin nínú ìtàn yìí?
2. Àwọn wo ló ńgbé agboolé kan náà?
3. Kí ló dé tí wọ́n fi kí Gbádé àti ìyàwó rẹ̀ kú oríìire?
4. Kí ló fà á tó fi jẹ́ pé bàbá-àgbà ló sọ ọmọ Gbádé lórúkọ?

**Ìpín 3: Àpèkọ**

Àwọn eèrà fọwọ́sowọ́pọ̀ láti wá oúnjẹ.

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Ìrànlọ́wọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́

Ọ̀ga ilé-ẹ̀kọ́ ṣe ìkéde pàtàkì fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Ó ní ìjọba ti pinnu láti dín owó-ẹ̀kọ́ kù. Ìjọba ti ní ìmọ̀lára ìyàn tó mú gbogbo ayé. Ìjọba ti ṣetán láti ṣe ìrànwọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Inú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dùn púpọ̀. Wọ́n dá músò, músò fún ìjọba.

★ Wọ́n ké músò, músò fún ìjọba.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







## Tàlà àti Tàfá

Tàlà àti Tàfá máa ń jókòó papọ̀ nínú yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́. Ní ọjọ́ kan, Tàlà jókòó sí àyè Tàfá. Tàfá sọ pé kí ó sún sí àyè rẹ̀. Tàlà kọ̀ kò dìde. Tàfá kò bínú. Olùkọ́ dé ibẹ̀, ó bá Tàlà wí. Tàlà padà sí àyè rẹ̀. Ó sì bẹ Tàfá pé kó má bìínú.

★ Olùkọ́ dé ibẹ̀, ó bá Tàlà wí.

## Ẹ̀kọ́ 3

## Ẹ̀kọ́ 4



# Olùlàjà́

Àwọn ilé-ẹ̀kọ́ méjì ń gbá bọ́ọ̀lù. Tàlà àti Tàfá wà papọ̀ ní ẹgbẹ́ kan. Tàfá ṣèèṣì gbá bọ́ọ̀lù àgbélẹ̀gbá sígbó. Ilé-ẹ̀kọ́ kejì fò fáyọ̀. Inú bí Tàlà, ó fi ìbínú ta Tàfá láyà, Àwọn méjèèjì ń wojú ara wọn pẹ̀lú ìbínú. Adarí-eré là wọ́n níjà. Láìpẹ́ Tàfá gba bọ́ọ̀lù wọle.

★ Inú bí Tàlà, ó fi ìbínú ta Tàfá láyà, Àwọn méjèèjì ń wojú ara wọn pẹ̀lú ìbínú.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2



# Ìjà Ilẹ̀

Àsìkò òjò ti bẹ̀rẹ̀. Tárá gbin àgbàdo sí àyè kékeré lẹ́gbẹ̀ẹ́ ilé wọn. Tàlà ní òun ló kọ́kọ́ roko ibẹ̀ láti dáko. Ọ̀rọ̀ yìí da aáwọ̀ sílẹ̀ láàrin wọn. Gbádé pè àwọn méjéèjì wọlé. Tárá rojọ́, Tàlà náà ro tirẹ̀. Gbádé pín ilẹ̀ náa sí ọ̀nà méjì. Wọ́n dúpẹ́, oníkálukú sì lọ dáko tirẹ̀.

★ Wọ́n dúpẹ́, oníkálukú sì lọ dáko tirẹ̀.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4



# Ológbò Tárá

Tárá ní ológbò funfun kan. Tárá máa ń gbé ológbò náà mọ́ra. Ìyá-àgbà ní kí Tárá ṣọ́ra fún èékánná ológbò. Èékánná ológbò le ṣe ìpalára fún ènìyàn. Tárá dúpẹ́, ó gbé ológbò lọ sí yàrá ìyá-àgbà. Ológbò pa èkúté ńlá nínú yàrá ìyá-àgbà. Inú ìyá-àgbà dùn, ó dúpẹ́ lọ́wọ́ Tárá.

★ Tárá dúpẹ́, ó gbéológbò lọ sí yàrá ìyá-àgbà.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







# Ajá Tárà

Tárá ní ajá dúdú kan. Ajá Tárá máa ń bá ará-ilé ṣeré, ṣùgbọ́n ó máa ń gbó mọ́ àjòjì. Ajá Tárá máa ń ṣọ́lé lọ́sàn-án àti lóru. Lọ́jọ́ kan, ẹnìkan fẹ́ bá Tárá jà. Ajá rẹ̀ gbó, ó lé e lọ. Tárá fọwọ́ pa á lórí. Ajá náà ju ìrù sí i.

★ Tárá ní ajá dúdú kan. Ajá Tárá gbó.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







# Ìjàpá Àti Ajá

Ìjàpá àti ajá jẹ́ ọ̀rẹ́. Ní ọjọ́ kan, wọ́n lọ kí ọ̀kẹ́rẹ́. Ọ̀kẹ́rẹ́ fún wọn ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ oúnjẹ. Ajá fẹ́ dá oúnjẹ náà jẹ́. Inú bí ìjàpá, ó sọ pé àdáję kò dára. Ajá bẹ ìjàpá pé kí ó má bìínú. Àwọn méjéèjì sì jọ jẹ oúnjẹ náà.

★ Inú bí ìjàpá, ó sọ pé àdáje̩ kò dára.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2



# Àwọn Ohun Ọ̀sìn Iyìọlá

Iyìọlá fẹ́ràn láti máa sin ohun ọ̀sìn. Iyìọlá ní ajá, ehoro àti ewúrẹ́. Lọ́jọ́ kan, Gbadé fi iná sóko ẹ̀bá ilé. Iná yìí wọnú ọgbà ohun ọ̀sìn Iyìọlá. Àwọn aládùúgbò ràn án lọ́wọ́ láti pa iná. Inú Iyìọlá dùn pé kò sí ohun-ọ̀sìn tó kú. Ó dúpẹ́ púpọ̀ lọ́wọ́ àwọn aládùúgbò.

★ Lọ́jọ́ kan, Gbadé fi iná sóko ẹ̀bá ilé.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

**Ìpín 1: Àyọkà**

**Ológbò Tárá**

Tárá ní ológbò funfun kan. Tárá máa ń gbé ológbò náà mọ́ra. Ìyá-àgbà ní kí Tárá ṣọ́ra fún èékánná ológbò. Èékánná ológbò le ṣe ìpalára fún ènìyàn. Tárá dúpẹ́, ó gbé ológbò lọ sí yàrá ìyá-àgbà. Ológbò pa èkúté ńlá nínú yàrá ìyá-àgbà. Inú ìyá-àgbà dùn, ó dúpẹ́ lọ́wọ́ Tárá.

**Ìpín 2: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Níbo ni ológbò ti pa eku?
2. Báwo ni ológbò ṣe máa ń ké?
3. Kí ni ìdí tí Tárá fi gbọ́dọ̀ ṣọ́ra fún èékánná ológbò?
4. Kí ló jẹ́ kí inú ìyá àgbà dùn?

**Ìpín 3: Àpèkọ**

Ajá fẹ́ jẹ gbogbo oúnjẹ.

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Sáà 2
# Ọsẹ̀ 1 - 10



# Igi Ọ̀pẹ

Oko ọ̀pẹ Gbádé tóbi púpọ̀. Àwọn òṣìṣẹ́ oko rẹ̀ sì pọ̀ rẹpẹtẹ. Wọ́n máa ń fi ẹyìn ṣe epo pupa. Tàfá àti Tàlà tẹ̀lé bàbá lọ sí ẹkù Gbádé. Wọn rí àwọn òṣìṣẹ́ tó ń fọ̀ epo. Tàfá kígbe, “Bàbá, ẹ wo bí odi-ẹyìn yìí ṣe tóbi tó”. Bàbá ra epo lóko Gbádé. Tàfá àti Tàlà bá bàbá gbé epo dé ilé.

★ Tàfá kígbe, "Bàbá, ẹ wo bí odi-ẹyìn yìí ṣe tóbi tó".

**Ẹ̀kọ́ 1**



## Ẹ̀kọ́ 2





## Oko Tàfá

Àgbẹ̀ aláròjẹ ni Tàfá. Ó gbin iṣu, àgbàdo, ẹ̀gẹ́ àti ẹ̀fọ́ sí oko rẹ̀. Ní ọdún yìí, irè oko Tàfá tóbi bọ̀kùà-bọkua. Àwọn ọlọ́jà rọ́ wá ra irè oko rẹ̀. Wọ́n ní, "Irè oko Tàfá dára yàtọ̀." Tàfá ta irè oko rẹ̀. Owó rẹpẹtẹ wọlé fún Tàfá. Tàfá di olówó tabua.

★ Wọ́n ní, "Irè oko Tàfá dára yàtọ̀."

## Ẹ̀kọ́ 3







## Ẹ̀kọ́ 4





# Oko Àgbàdo

Tàlà àti Tárá dá oko àgbàdo. Àgbàdo náà hù, wọ́n sì róko sí i. Lọ́jọ́ kan, Tàlà àti Tárá lọ wo oko wọn. Àgbàdo wọn ti gbó. Wọ́n ya àgbàdo wá sílé. Ìyá wọn yẹ̀ ẹ́ wò. Ó ní, “Ẹ wo, ọlọ́mọ-ṣíkàtà yìí bó ṣe tóbi tó”. Tàlà àti Tárá sè àgbàdo díẹ̀ jẹ. Wọ́n sì tà ìyókù.

★ Ìyá wọn yẹ̀ ẹ́ wò. Ó ní, "Ẹ wo, ọlọ́mọ-ṣíkàtà yìí bó ṣe tóbi tó".

**Ẹ̀kọ́ 1**



## Ẹ̀kọ́ 2





# Ọ̀gẹ̀dẹ̀

Gbádé gbin ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà, ọ̀gẹ̀dẹ̀ ọ̀mìnì àti páráńtà sí oko rẹ̀. Tàlà àti Tárá gbádùn dòdò àti ìrẹsì púpọ̀. Tàlà tẹ̀lé Gbádé lọ sí oko ọ̀gẹ̀dẹ̀. Tárá ní, “Ọ̀gẹ̀dẹ̀ yìí ti pọ́n o. A máa jẹ dòdò àti ìrẹsì lónìí.” Gbádé dáhùn pé, “Ọ̀gẹ̀dẹ̀ páráńtà lèyí. Ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà ni a máa ń fi dín dòdò!”

★ Tárá ní, “Ọ̀gẹ̀dẹ̀ yìí ti pọ́n o. A máa jẹ dòdò àti ìrẹsì lónìí.”

**Ẹ̀kọ́ 3**



## Ẹ̀kọ́ 4









# Ìtọ́jú Oúnjẹ

Ìyá Tárá lọ ra nńkan ọbẹ̀ lọ́jà. Ó ra ẹran, ẹja àti edé. Tárá fi omi ṣan ẹran, ẹja àti edé tí ìyá rà. Ó bọ ẹran, ó sì dín edé àti ẹja. Tárá ní, “Háà! Mo gbádùn ẹran díndín púpọ̀.” Ìyá Tárá se ọbẹ̀ àdídùn. Ó sì gbé e sínú ẹ̀rọ-amóhun-tutù.

★ Tárá ní, “Háà! Mo gbádùn ẹran díndín púpọ̀.”

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2





# Tàlà Fakọyọ

Tàlà fẹ́ràn ẹ̀kọ́-oúnjẹ́-sísè. Olùkọ béèrè àwọn ọ̀nà ìpamọ́ oúnjẹ ti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀. Tàlà ní, “A lè dín ẹja tàbí ká yan án. A lè bọ ẹran tàbí ká fiyọ̀ pò ó.” Ó tún sọ pé, “A sì lè kó oúnjẹ sínú ẹ̀rọ-amóhun-tutù.” Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pàtẹ́wọ́ fún un. Dára ní, “Háà! O ti fẹ́ràn oúnjẹ jù.”

★ Tàlà ní, "A lè dín ẹja tàbí ká yan án. A lè bọ ẹran tàbí ká fiyọ̀ pò ó."

**Ẹ̀kọ́ 3**







## Ẹ̀kọ́ 4









# Ìtọ́jú Oúnjẹ

Gbádé wá fún àwọn ará abulé ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìpamọ́ oúnjẹ. Ó sọ pé, “A lè gbé oúnjẹ sínú ẹ̀rọ-amóhun-tutù. A lè fi ẹ̀rọ lọ ẹ̀gúsí, ẹja gbígbẹ àti edé. A lè fi ayanran ìgbàlódé yan ẹran.” Inú àwọn ará abúlé dùn. Wọ́n dúpẹ́ púpọ̀ lọ́wọ́ Gbádé. Ìyá tárá sọ pé, “Àṣé orísi ọ̀nà ni a lè gbà tọ́jú oúnjẹ.”

★ Ìyá tárá sọ pé, "Àṣé oríṣi ọ̀nà ni a lè gbà tọ́jú oúnjẹ."

**Ẹ̀kọ́ 1**







## Ẹ̀kọ́ 2









## Oníyán Ewé

Iyìọ̀lá jẹ́ gbajúmọ̀ oníyán ní ìlú Owóde. Iyán Iyìọ̀lá máa ń gbóná fẹlifẹli. Dára fẹ́ mọ ohun tí ó jẹ́ kí iyán rẹ̀ máa gbóná. Iyìọ̀lá ṣàlàyé fún un pé ẹ̀rọ ìgúnyán ìgbàlóde ni òun máa ń lò. Dára ní, "Ó ga o. Àṣé ayé ti dẹrùn báyìí." Inú rẹ̀ dùn, ó sì dúpẹ́ lọ́wọ́ Iyìọ̀lá.

★ Dára ní, "Ó ga o. Àṣẹ́ ayé ti dẹrùn báyìí."

## Ẹ̀kọ́ 3



## Ẹ̀kọ́ 4



# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

| Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà |
| --- |
| |

**Ìpín 1: Àyọkà**

**Oko Tàfá**

Àgbẹ̀ alárojẹ ni Tàfá. Ó gbin iṣu, àgbàdo, ẹ̀gẹ́ àti ẹ̀fọ́ sí oko rẹ̀. Ní ọdún yìí, irè oko Tàfá tóbi bọ̀kùà-bọkua. Àwọn ọlọ́jà rọ́ wá ra irè oko rẹ̀. Wọ́n ní, "Irè oko Tàfá dára yàtọ̀." Tàfá ta irè oko rẹ̀. Owó rẹpẹtẹ wọlé fún Tàfá. Tàfá di olówó tabua.

**Ìpín 2: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Iṣẹ́ wo ni Tàfá ń ṣe?
2. Dárúkọ ohun ọ̀gbìn méta tí Tàfá gbìn sí oko rẹ̀?
3. Kí ni ìdí tí àwọn ọlọ́jà fi rọ́ wá ra irè oko Tàfá?
4. Báwo ni Tàfá ṣe di olówó tó?

**Ìpín 3: Àpèkọ**

Tárá ní, "Háà! Mo gbádùn ẹran díndín púpọ̀." Ìyá Tárá se ọbẹ̀ àdídùn.

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Tàlà àti Tárá

Ní ọ̀sán ọjọ́ Ajé, Tàlà àti Tárá ń padà bọ̀ láti ilé-ẹ̀kọ́. Wọ́n ń jíròrò lórí ohun tí olùkọ́ kọ́ wọn. Òjò ń rọ̀ díẹ̀díẹ̀. Tàlà béèrè pé, “Ǹjẹ́ o mọ̀ pé òjò lè fa ìkún-omi?” Tárá ní, “Bẹ́ẹ̀ ni, ìkún-omi léwu púpọ̀.” Àwọn méjèèjì gbà pé líla gọ́tà káàkiri ìlú ṣe pàtàkì láti dẹ́kun ìkún-omi gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ ṣe sọ.

★ Tàlà béèrè pé, "Ǹjẹ́ o mọ̀ pé òjò lè fa ìkún- omi?"

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2









## Odò Ọya

Olùkọ́ bèèrè pé, "Kí ni ẹ mọ̀ nípa Odò Ọya?" Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wo ara wọn lójú. Olùkọ́ kọ́ wọn pé Odò Ọya ni odò tó tóbi jù ní orílẹ̀-èdè Nàìjíría. Odò yìí la orílẹ̀-èdè márùn-ún kọja. Ó sì ṣàn kọjá ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìpínlẹ̀ ní Nàìjíríà. Odò yìí ni orísun iná-mọ̀nàmọ́ná fún orílẹ̀-èdè yìí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ará-ìlú ló sì máa ń pẹja nínú odò yìí.

★ Olùkọ́ bèèrè pé, “Kí ni ẹ mọ̀ nípa Odò Ọya?”

**Ẹ̀kọ́ 3**



## Ẹ̀kọ́ 4









# Òkè Olúmọ

Tárá àti Tàlà rí àwòrán Òkè Olúmọ nínú ìwé. Tárá ní, "Tàlà, ǹjẹ́ o ti gbọ́ nípa òkè yìí rí?" Tàlà sọ pé òun kò gbọ́ rí. Wọ́n kà á pe Olúmọ ti di ibi ìgbafẹ́ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn. Wọ́n bẹ àwọn òbí wọn láti mú wọn lọ wo Òkè Olúmọ ní ìlú Abẹ́òkúta. Wọ́n rí orísìrísì àpáta àti àwọn ohun ìṣẹ̀ǹbáyé.

★ Tárá ní, “Tàlà, ǹjẹ́ o ti gbọ́ nípa òkè yìí rí?”

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2





## Odò Owódé

Gbádé bá Tàlà àti Tárá lọ sí odò Owódé. Odò yìí tóbi púpọ̀. Wọn rí àwọn ọmọdé tó ń lúwẹ̀ẹ́. Tárá ní, “Ṣé gbogbo àwọn ọmọ yìí ló mọ̀wẹ̀?” Gbádé sọ pé kò dára fún ẹni tí kò bá mọ̀wẹ̀ láti wọnú odo. Wọ́n gbọ́ igbe ọmọdé kan. Ọmọdé yìí kò mọ̀wẹ̀ dáradára. Gbádé bẹ́ lu odò, ó sì fa á jádé.

★ Tárá ní, “Ṣé gbogbo àwọn ọmọ yìí ló mọ̀wẹ̀?”

**Ẹ̀kọ́ 3**



## Ẹ̀kọ́ 4





# Iṣu àti Ẹ̀wà

Bàbá Tárá àlèjò ọ̀rẹ́ rẹ̀ mẹ́fà lálejò. Ìyá Tárá kí wọn káàbọ̀. Ó sì sáré lọ bẹ iṣu mẹ́ta sórí iná. Ó la iṣu kọ̀ọ̀kan sí mẹ́jọmẹ́jọ. Tárá ni, “Agolo ẹ̀wà mélòó ni kí ń sè o? Ìyá ní, “Agolo mẹ́wàá.” Láìpẹ́ oúnjẹ ti jinná. Ẹ̀là iṣu mẹ́rinmẹ́rin ni ẹni kọ̀ọ̀kan fi jẹ ẹ̀wà. Gbogbo wọn gbádùn oúnjẹ náà.

★ Tárá ni, "Agolo ẹ̀wà mélòó ni kí ń sè o?

## Ẹ̀kọ́ 1







## Ẹ̀kọ́ 2





# Ìmọ̀ Ònkà

Tárá bèèrè lọ́wọ́ Tàlà pé, “Kí ni ẹẹ́wàá lọ́nà mẹ́ta?” Tàlà ṣa ọ̀pọ̀lọpọ̀ òkúta wẹ́wẹ́ jọ. Ó ka òkúta mẹ́wàá-mẹ́wàá sí ọ̀nà mẹ́ta. Lẹ́yìn èyí, ó ní kí Tárá ka gbogbo àwọn òkúta yìí papọ̀. Ó ní, “Tàlà, ọgbọ̀n ni ẹyọ òkúta tó wà níbí o.” Tàlà ni, “O káre, bẹ́ẹ̀ ni, ọgbọ̀n ni ẹẹ́wàá lọ́nà mẹ́ta.”

★ Tárá bèèrè lọ́wọ́ Tàlà pé, “Kí ni ẹ̀ẹ́wàá lọ́nà mẹ́ta?”

Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4





# Aránṣọ

Dára ra aṣọ ọ̀pá mẹ́ta. Ó gbé aṣọ náà fún aránṣọ. Aránṣọ wọn Dára àti aṣọ rẹ̀. Aránṣọ rán aṣọ fún Dára. Ìbú àti òòró aṣọ ṣe rẹ́gí. Dára bèèrè pe, “Èló lowó iṣẹ́ o?” Aránṣọ sọ pe, “Ẹgbẹ̀fà naira ni o.” Dára ná owó-iṣẹ́ si ẹgbẹ̀rin naira. Ó fún aránṣọ ní ẹgbẹ̀rún náírà. Aránṣọ fún un ní igba náírà padà.

★ Dára bèèrè pe, “Èló lowó iṣẹ́ o?”

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2





# Ìyá Àgbà àti Dárà

Ìyá-àgbà rán Dára ní ìgò epo kan. Ó fún un ní igba náírà. Dára ra epo ọgbọ̀n náírà. Elépo bi í pé, “Ìgò rẹ dà?” Elépo fi àrọ rọ epo náà sínú ìgò. Dára gbé epo lọ fún ìyá-àgbà. Ó kó ṣẹ́ǹjì fún ìyá-àgbà. Ìyá àgbà bi í pé, “Èló nì èyí?” Dára ní àádọ́sàn-án náírà. Ìyá àgbà ní, “O káre!”

★ Ó kó ṣẹ́ńjì fún ìyá-àgbà. Ìyá àgbà bi í pé, “Èló nì èyí?”

## Ẹ̀kọ́ 3



# Ẹ̀kọ́ 4



# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

**Ìpín 1: Àyọkà**

**Aránṣọ**

Dára ra aṣọ ọ̀pá mẹ́ta. Ó gbé aṣọ náà fún aránṣọ. Aránṣọ wọn Dára àti aṣọ rẹ. Aránṣọ rán aṣọ fún Dára. Ìbú àti òòró aṣọ ṣe rẹ́gí. Dára bèèrè pe, "Èló lowó iṣẹ́ o?" Aránṣọ sọ pe, "Ẹgbẹ̀fà naira ni o." Dára ná owó-iṣẹ́ si ẹgbẹ̀rin naira. Ó fún aránṣọ ní ẹgbẹ̀rún náírà. Aránṣọ fún un ní igba náírà padà.

**Ìpín 2: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Ọpá aṣọ mélòó ni Dára gbé fún Aránṣọ?
2. Kí ni ìdí tí aránṣọ fi wọn Dára?
3. Kí ni ìdí tí aránṣọ fi fún Dára ní igba náírà padà?
4. Èló ni ó ṣẹ́kù tí a bá yọ naira méjì kúrò nínú naira maẹ́fà?

**Ìpín 3: Àpèkọ**

Tárá ní, "Tàlà, ǹjẹ o ti gbọ́ nípa òkè yìí rí?"

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Sáà 3
# Ọ̀sẹ̀ 1 - 10



# Fọ́lákẹ́ lọ sí Ìlú-ọba

Fọlákẹ́ kò wọnú ọkọ̀ òfurufú rí. Ojú òfurufú nìkan ló ti máa ń rí i. Ó wu Fọlákẹ́ láti wọ ọkọ̀ òfurufú. Ṣadé ẹ̀gbọ́n rẹ̀ wá sílé láti Ìlú-ọba. Ṣadé ṣètò fún Fọlákẹ́ láti tẹ̀síwájú nínú ẹ̀kọ́ rẹ̀ ní Ìlú-ọba. Ó gba ìwé ìrìnnà fún Fọlákẹ́. Wọ́n lọ wọ ọkọ̀ òfurufú ni ọjọ́ Ajé. Fọlákẹ́ ní, ah! Ọkọ̀ yìí mà tóbi gan-an o! Ó ní, "ohun alárànbarà máà pọ̀ nínú ọkọ̀ òfurufú yìí o!". Ó sì pinnu láti di awakọ̀ òfúúrufú.

★ Fọlákẹ́ ní, ah! Ọkọ̀ yìí mà tóbi gan-an o.

Ẹ̀kọ́ 1







## Ẹ̀kọ́ 2





# Ìjọba Ran Ẹgbẹ́ Awakọ̀ lọ́wọ́

Àwọn awakọ̀ kò rí ọkọ̀ tuntun wà mọ́. Àwọn àlòkù ọkọ̀ ni wọ́n ń rà ní àtọwọ́dọ́wọ́. Bádéjọ alága ẹgbẹ́ awakọ̀ ní, “Èyí mà sú mi o!” Bádéjọ kọ̀wé sí Gómìnà fún ìrànlọ́wọ́. Ìjọba fún ẹgbẹ́ awakọ̀ ní ọkọ̀-akérò mẹ́wàá. Inú àwọn awakọ̀ dùn. Alága ní, “mo dúpẹ́ gidi gan-an lọ́wọ́ Gómínà wa!”. Àwọn náà dín owó ọkọ̀ kù fún àwọn ará-ìlú. Inú àwọn ará-ìlú dun. Wọ́n ń jẹ èrè ìjọba olóṣèlú.

★ Bádéjọ alága ẹgbẹ́ awakọ̀ ní, "Èyí mà sú mi o!"

**Ẹ̀kọ́ 3**



# Ẹ̀kọ́ 4





# Tárá Wọkọ̀ Ojú-Omi

Tárá jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ Owódé. Ó ń gbé lọ́dọ̀ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ obìnrin. Olùkọ́ wọn ti kọ́ wọn nípa àwọn ohun ìrìnnà. Ó wu Tárá láti wọkọ̀ ojú-omi. Ó sì sọ fún ẹ̀gbọ́n rẹ̀. Ní ọjọ́-ìbí Tárá, ẹ̀gbọ́n rẹ̀ mú u lọ sí èbúté. Inú Tárá dùn, ó ní, "ah! ọkọ̀ ojú-omi mà pọ̀ ní èbúté yìí o!" Ó wọ inú ọkọ̀ ojú-omi kan. Ó ní, "Àṣẹ bí ọkọ̀ ojú-omi ṣe rí rè é!"

★ Ó ní, "Àṣẹ́ bí ọkọ̀ ojú-omi ṣe rí rè é!"

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2





# Ọkọ̀-ojú-irin

Tàlà rí àwòran ọkọ̀-ojú-irin. Ó yà á lẹ́nu bí ó ṣe gùn tó.Ó ní, “ah! ọkọ̀ yìí máà gùn o!” Lọ́jọ́ kan, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọ ọkọ̀-ojú-irin lọ sókè-ọya. Tàlà pàdé Tàfá ní ìdíkọ. Tàlà ni, “Tàfá! Ojú rẹ nìyí!” Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ fẹ́ràn bí ọkọ̀ ti ń ṣe “Faka-fìkì, faka-fìkì” lọ. Wọ́n sì ń kọ orin bayìí:

Mo lè gòke
Mo lè sọ̀
Òkè tálájàpá kò le gùn
Mo ti gùn, mo ti sọ̀
Faka fìkì
Faka fìkì.

★ Tàlà ni, "Tàfá! Ojú rẹ nìyí!"

**Ẹ̀kọ́ 3**



## Ẹ̀kọ́ 4






# Ayẹyẹ Ọjọ́-ìbí

Ayẹyẹ ọjọ́-ìbí Tárá àti Tàlà ń bọ̀ lọ́nà. Àwọn òbí wọn pinnu láti ṣe ayẹyẹ ọjọ́ náà fún wọn. Àwọn ọlọ́jọ́-ìbí fi àtẹ̀jíṣẹ́ pe Tàfá àti Dára síbi ayẹyẹ. Gbádé sanwó ìkéde ayẹyẹ yìí lóri rédíò. Iyìọlá fi àwòrán àwọn ọlọ́jọ́-ìbí sórí ẹ̀rọ ayélujára. Nígbà tí wọ́n tún rí fọ́tò ara wọn lórí ẹ̀rọ-amóhùn-máwòrán, wọ́n ni, “Háà! Èyí kàmọ̀mọ̀ o!” Lọ́jọ́ ayẹyẹ, gbogbo ènìyàn jẹun, wọ́n jó, wọ́n sì ya fótò. Àwọn àlejò tó wá ní, “ah! òbí àwọn ọmọ yíí máà ṣe bẹbẹ o!”

★ "Háà! Èyí kàmọ̀mọ̀ o!"

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2





# Àrùn Kòrónà

Kére o! Ìjọba ní kí gbogbo ènìyàn gbélé wọn nítorí àrùn kòrónà tó gbòde kan. Tàlà àti Tárá gbọ́ nípa ìkéde yìí lóri rédíò. Tárá kígbe, “Yéè! Àrùn yìí mà burú o!” Tàlà lo ẹ̀rọ-alágbèéká bàbá wọn láti yẹ ìròyìn náà wò lórí ẹ̀rọ̀-ayélujára. Ó rí i pé àrùn yìí ti gbilẹ̀ kárí ayé. Ìjọba ti bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe ìkéde lórí ẹ̀rọ rédíò àti ẹ̀rọ-amóhùnmáwòrán pé kí oníkálukú wà ní ìpamọ́ nínú ilé wọn. Ojoojúmọ́ sì ni wọ́n ń gbé ìròyìn ìtanijí jáde lórí àrùn náà.

★ Tárá kígbe, “Yéè! Àrùn yìí mà burú o!”

Ẹ̀kọ́ 3



## Ẹ̀kọ́ 4









# Dára Gba Ẹ̀bùn Ẹ̀kọ́-Ọ̀fẹ́

Dàda ka ìkéde ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ́ nínú ìwé-ìròyìn. Ó forúkọ Dára ọmọ rẹ̀ sílẹ̀ lórí ẹ̀rọ-ayélujára. Ẹ̀rọ kọ̀m̀pútà ni wọn yóò fi ṣe ìdánwò náà. Háà! Dára kò lo ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà rí! Tàlà fún un ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ọlọ́jọ́-méjì. Dára sì ṣe ìdánwò náà lórí ẹ̀rọ-ayélujára. Ọjọ́ kejì ni èsì ìdánwò jáde. Dára yege ìdánwò. Ìjọba kéde lórí rédíò pé Dára ló gbé ipò kìn-ín-ní. Wọ́n sì fún un ní ẹ̀bùn ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ. Tàlà ni, “ah! O kú Oríire ọ̀rẹ́.

# ★ Háà! Dára kò lo ẹ̀rọ kọ̀m̀pútà rí!

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2





# Wíwáṣẹ́

Ààyè iṣẹ́ ṣí sílẹ̀ ní ilé-iṣẹ́ ìtẹ̀wé kan. Gbádé gbọ́ ìkéde nípa iṣẹ́ yìí lórí ẹ̀rọ rédíò. Ó kọ ìwé ìwáṣẹ́ ránṣẹ́ sílé iṣẹ́ náà. Ilé-iṣẹ́ ìtẹ̀wé yìí pe Gbádé fún ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò. Iyìọ̀lá júwe ibi tí ilé-iṣẹ́ náà wà fún un. Gbádé rí pátákó-ajúwe ilé-iṣẹ́ náà. Wọ́n ṣe ìdánwò lórí ẹ̀rọ kọ̀m̀pútà. Gbádé yege, wọ́n sì fún un ní ìwé ìgbanisíṣẹ́. Gbádé ní, “Ọlọ́run mo dúpẹ́ o!”. Iyìọ̀lá kí Gbádé, “ẹ kú oríire o!”.

★ Gbádé ni, "Ọlọ́run mo dupẹ o!"

## Ẹ̀kọ́ 3



## Ẹ̀kọ́ 4



# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

**Ìpín 1: Àyọkà**

**Tárá Wọkọ̀ Ojú-Omi**

Tárá jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ Owódé. Ó ń gbé lọ́dọ̀ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ obìnrin. Olùkọ́ wọn ti kọ́ wọn nípa àwọn ohun ìrìnnà. Ó wu Tárá láti wọkọ̀ ojú-omi. Ó sì sọ fún ẹ̀gbọ́n rẹ̀. Ní ọjọ́-ìbí Tárá, ẹ̀gbọ́n rẹ̀ mú u lọ sí èbúté. Inú Tárá dùn, ó ní, "ah! ọkọ̀ ojú-omi máà pọ̀ ní èbúté yìí o!" Ó wọ inú ọkọ̀ ojú-omi kan. Ó ní, "Àṣé bí ọkọ̀ ojú-omi ṣe rí rè é!"

**Ìpín 2: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Ilé-ẹ̀kọ́ wo ni Tárá ń lọ?
2.Níbo ni àwọn ọkọ̀ ojú-omi máa ń gúnlẹ̀ sí?
3. Kí ni ìdí tí Tárá fi fi ìyàlẹ́nu han?
4. Dárúkọ ohun ìrìnnà mẹ́ta tí o mọ̀.

**Ìpín 3: Àpèkọ**

Wọ́n lọ wọ ọkọ̀ òfurufú ni ọjọ́ Ajé. Fọlákẹ́ ní, ah! Ọkọ̀ yìí mà tóbi gan-an o! Ó ní, "ohun aláràmbarà máà pọ̀ nínú ọkọ̀ òfurufú yìí o!"

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Ìbẹ̀wò Woléwolé

Woléwolé wá sí àdúgbò Tárá ní àárọ̀ ọjọ́ kan. Tárá ló kọ́kọ́ rí wọn. Ó ní: 'Háà, wàhálà dé!' Ó sáré lọ sọ fún Iyìọlá. Iyìọlá àti àwọn aráalé yára ń palẹ̀ àyíka ilé mọ́. Ìdọ̀tí ṣì pọ̀  káàkiri nílẹ̀. Bí wọ́n ti fẹ́ máa gbálẹ̀ ni woléwolé wọlé. Ó ní "Ṣé ẹ kò mọ̀ pé ẹ̀gbin àyíká lè ṣokùnfà àìsàn ni?" Tárá àti àwọn aráalé tètè ń tún àyíká wọn ṣe.

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2





# Ìtọ́jú Àyíká Wa

Tárá mú ìgbálẹ̀ lọ́wọ́ lẹ́bàá gọ́tà tí omi ilé-ìdáná dágún sí. Iyìọ̀lá ké mọ́ Tárá. Ó ní 'Kí lò ń ṣe níbẹ̀ yẹn? Ṣọ́ra kí o má lọ yọ́ ṣubú o!' Tárá dáhùn pé òun fẹ́ fọ gọ́tà ni. Ó ní olùkọ́ kọ́ wọn kí wọ́n máa fọ gọ́tà àyíká ilé wọn. Tàlà lọ pọn omi. Ó ní òun náà fẹ́ lọ fọ ilé-ìgbọ̀nsẹ̀ wọn. Inú ìyá wọn dùn, ó gbé òṣùbà fún olùkọ́ Tàlà àti Tárá.

## Ẹ̀kọ́ 3







## Ẹ̀kọ́ 4





# Àǹfààní Ìwẹ̀ Wíwẹ̀

Ọ̀rẹ́ Tàlà kórìíra ìwẹ̀ wíwẹ̀. Kì í wẹ̀ déédéé. Lọ́jọ́ kan, Tàlà àti ọ̀rẹ́ rẹ̀ jọ ń ṣeré. Tàlà bẹ̀rẹ̀ sí í gbọ́ òórùn ara ọ̀rẹ́ rẹ̀. Tàlà fi ọgbọ́n sọ fún un pé ó yẹ kí wọ́n lọ wẹ̀ nítorí ooru tó mú. Tàlà gba ọ̀rẹ́ rẹ̀ nímọ̀ràn pé ìwẹ̀ wíwẹ̀ ṣe pàtàkì. Àìwẹ̀ déédé máa ń kóbá àlàáfíà ara. Nígbà tí ọ̀rẹ́ rẹ̀ délé, ó gbé omi, ó sì wẹ̀.

## Ẹ̀kọ́ 1







## Ẹ̀kọ́ 2





# Ìtọ́jú Oúnjẹ

Lọ́jọ́ kan, Iyìọ̀lá se oúnjẹ. Ó bù oúnjẹ sínú àwo ṣùgbọ́n kò dé e. Eṣinṣin bà lé oúnjẹ yìí. Tárá jẹ oúnjẹ nígbà tó dé láti ilé-ẹ̀kọ́. Lọ́jọ́ kejì, Tárá bẹ̀rẹ̀ sí í yàgbẹ́, ó ń bì. Ẹ̀rù ba Iyìọ̀lá. Wọ́n gbé Tárá lọ sí ilé-ìwòsàn. Dókítà sọ pé àrùn-onígbáméjì ni Tárá ní. Dókítà tọ́jú Tárá. Ó kìlọ̀ fún Iyìọ̀lá kó máa dé oúnjẹ. Ara Tárá yá, ó padà sílé.

## Ẹ̀kọ́ 3







## Ẹ̀kọ́ 4





# Líṣàbi Agbòǹgbò Àkàlà

Akíkanjú jagunjagun ni Líṣàbí ní ìlú Ẹ̀gbá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ogun ló ti ṣẹ́ fún wọn. Nígbàkúgbà tí ogun bá wọ ìlú Ẹ̀gbá, Líṣàbí á kó àwọn ọmọ-ogun jọ. Wọn a fi ìgboyà kojú ọ̀tá. Wọ́n á bá wọn fìjà péẹ́ta. Àwọn ogun yìí máa ń gbóná púpọ̀! Ṣùgbọ́n Líṣàbí kì í sá lójú ìjà. Líṣàbí a kẹ́rú, a kẹ́rù wọ̀lú. Àlàáfíà dé sí ìlú Ẹ̀gbá. Inú gbogbo ìlú dùn sí Líṣàbí. Ọba sì dá Líṣàbí lọ́lá.

## Ẹ̀kọ́ 1



## Ẹ̀kọ́ 2









# Fúnmiláyọ̀ Kútì

Akíkanjú obìnrin ni Fúnmiláyọ̀ Kútì nílùú Ẹ̀gbá. Ó kàwé, ó sì ní òkìkí. Òun ni obìnrin tó kọ́kọ́ wa ọkọ̀ lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà! Fúnmiláyọ̀ Kútì kópa nínú ètò ìṣèjọba ìlú Ẹ̀gbá. Ó jà láti mú ayé rọrùn fún àwọn obìnrin. Ìjà náà jẹ́ kí àwọn obìnrin ìlú Ẹ̀gbá ní òmìnira. Inú àwọn obìnrin ìlú dùn. Gbogbo wọ́n dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ̀. Ìjọba forúkọ ilé-ẹ̀kọ́ kan sọrí Fúnmiláyọ̀ Kútì.

## Ẹ̀kọ́ 3



## Ẹ̀kọ́ 4





# Mọ́remí Akínkanjú Obìnrin

Olorì Ọọ̀ni Aláyémọrẹ ni Mọ́remí. Mọ́remí jẹ́ arẹwà obìnrin. Láyé àtijọ́, àwọn kan máa ń kógun ja Ilé-Ifẹ̀. Lọ́jọ́ kan, wọ́n tún wá láti kó Ilé-Ifẹ̀ lẹ́rú. Mọ́remí jọ̀wọ́ ara rẹ̀, wọ́n sì mú u lọ. Ẹwà Mọ́remí wu ọba ìlú yìí, ó sì fi Mọ́remí ṣaya. Mọ́remí gbé láàrin wọn. Láìpẹ́ ó mọ àṣírí wọn, ó sì sá wálé. Ó ṣáájú ogun Ilé-Ifẹ̀ láti ṣẹ́gun ọ̀tá. Inú àwọn Ilé-Ifẹ̀ dùn púpọ̀.

## Ẹ̀kọ́ 1







## Ẹ̀kọ́ 2





# Ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwúrà

Akínkanjú obìnrin ni Ẹfúnṣetán Aníwúrà. Oníṣòwò tó rí tajé ṣe ni. Ó jẹ́ ọmọ ìlú Ìbàdàn. Lásìkò ìṣèjọba ààrẹ Látòòsà, Ẹfúnṣetán ṣe gudugudu méje. A máa fi owó àti oúnjẹ ran àwọn jagungagun Ìbàdàn lọ́wọ́. Ìrànwọ́ owó yìí ni wọ́n fi ń ra ẹ̀tù, àhàyá àti ìbọn. Ẹfúnṣetán tún jẹ́ olówò ẹrú. Ọlá àti ẹ̀mí ìlawọ́ rẹ̀ ló mú kí wọ́n fi oyè Ìyálóde Ìbàdàn dá a lọ́lá.

## Ẹ̀kọ́ 3



## Ẹ̀kọ́ 4



# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

**Ìpín 1: Àyọkà**

**Àǹfààní Ìwẹ̀ Wíwẹ̀**

Ọ̀rẹ́ Tàlà kórìíra ìwẹ̀ wíwẹ̀. Kì í wẹ̀ déédéé. Lọ́jọ́ kan, Tàlà àti ọ̀rẹ́ rẹ̀ jọ ń ṣeré. Tàlà bẹ̀rẹ̀ sí í gbọ́ òórùn ara ọ̀rẹ́ rẹ̀. Tàlà fi ọgbọ́n sọ fún un pé ó yẹ kí wọ́n lọ wẹ̀ nítorí ooru tó mú. Tàlà gba ọ̀rẹ́ rẹ̀ nímọ̀ràn pé ìwẹ̀ wíwẹ̀ ṣe pàtàkì. Àìwẹ̀ déédé máa ń kóbá àlàáfíà ara. Nígbà tí ọ̀rẹ́ rẹ̀ délé, ó gbé omi, ó sì wẹ̀.

**Ìpín 2: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Ta ni kò fẹ́ràn láti máa wẹ̀?
2. Dárúkọ ohun mẹ́ta tí àìwẹ̀ lè fà sí àgọ́ ara.
3. Sọ ohun mẹ́rin tí a máa ń fi wẹ̀.
4. Orúkọ wo ni a lè pe ẹni tí ó fẹ́ràn ìmọ́tótó?

**Ìpín 3: Àpèkọ**

Ó jẹ́ ọmọ ìlú Ìbàdàn. Lásìkò ìṣèjọba ààrẹ Látòòsà, Ẹfúnṣetán ṣe gudugudu méje.

**Àríwísí Olùkọ́:**

— Not for Sale —

PBYP3